1172

William Bascom, Director
Museum of Anthropology
University of California
Berkeley 4, California

*Number One*

# BI A TI ṢE IKỌ LẸTA LI EDE YORUBA

A ṢE IWE YI LATI ỌWỌ AWỌN IGBIMỌ ẸKUṄ ỌYỌ TI NṢE IWE KIKA LI EDE YORUBA

*Iye Owo:* KỌBỌ 3D MẸTA

# BI A TI ṢE IKỌ LẸTA

# LI EDE YORUBA

# ỌRỌ IṢIWAJU

GBOGBO wa ni a fẹ ati mã ri lẹta gba, ṣugbọn a ko le ni ireti pe a o mã ri ọpọlọpọ iwe bẹ̃ gba, bi ko ṣe pe awa nã ba nkọ diẹdiẹ si enia.

O wá buru wipe ni apa ilu wa yi, ogunlọgọ enia li o wà ti ko mọ iwe ikọ rara, tabi ti o jẹ pe ọ̀ye diẹ ni nwọn ni nipa bi a ti ṣe ikọwe si enia li ọna ti o dara.

Nitori gbogbo awọn enia wọnyi ati ni pataki nitori awọn agbalagba wọ̃nni, li ọkunrin ati li obinrin, ti wọn ṣẹṣẹ kọ́ iwe kika ati kikọ tan ni a ṣe ṣe iwe kekere yi.

Njẹ ninu iwe yi ni ẹ o ti-ri awọn ilana kekeke melokan ti yio fi ye yin bi a ti ṣe ikọwe si ara ẹni. Bi ẹ ba fi ibaralẹ ati ọ̀ye ka wọn, ki yio pẹ ki ẹ to le mã kọ iwe si enia li-ọna ti o dara.

Ọgbẹni Alagba ti awọn *Igbimo Ti Nse Iwe Kika Li Ede Yoruba*, ti o wà ni Ibadan, li o kọ́kọ́ kọ awọn ilana wọnyi li ede Gẹsi. Ọgbẹni J. O Fanẹyẹ, Akọwe Onidajọ, ti o ti jẹ ọkan ninu awọn Igbimọ nã ri, li o ṣe itumọ awọn ilana nã si ede Yoruba.

E. A. L. GASKIN

Alabojuto Ile Ẹkọ

*Alaga fun awon Igbimo Ekun Oyo ti nse Iwe Kika Li Ede Yoruba*

Ibadan, Ọjọ 26, Oṣu Oct. 1945.

# AWỌN OHUN TI O WA NINU IWE YI

## Ori Kini

Oju Iwe

IDI RẸ TI O FI TỌ KI A MA KỌ LẸTA SI ENIA FUN ARA ẸNI .... .... .... .... .... 4

## Ori Keji

ONIRURU IPA TI MBẸ NINU LẸTA .... .... .... 6

## Ori Kẹta

ỌRỌ IKI--NI: BI A TI ṢE IBẸRẸ LẸTA ATI BI A TI ṢE IPARI RẸ .... .... .... .... .... 11

## Ori Kẹrin

ONIRURU LẸTA TI A NKỌ SI ENIA .... .... .... 12

## Ori Karun

APẸRẸ ONIRURU LẸTA TI A NKỌ SI ENIA .... .... 15